# ITỌJU AWỌN ALUFAA ATI AWỌN ỌMỌ LEFI
## Numeri 18:1-32
### ẸKỌ 98 – FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSỌRI: "Ẹ fifun ni, a o si fifun nyin" (Luku 6:38).**

**Iṣẹ Awọn Ọmọ Lefi**

Awọn ọmọ Lefi ti ya ara wọn sọtọ fun iṣẹ pataki fun Ọlọrun; Ọlọrun si ti fi aye silẹ fun wọn lati maa ṣiṣẹ isin ninu Ile Rẹ. Iṣẹ wọn ni lati maa ran awọn alufaa lọwọ ninu ijọsin agọ ajọ pẹlu gbigbe agọ naa nigbakugba ti awọn Ọmọ Israẹli ba n lọ ni irin ajo wọn. Lẹyin naa nigba ti awọn Ọmọ Israẹli de Ilẹ Ileri, a ya awọn idile kan sọtọ ninu ẹya Lefi fun iṣẹ isin ti orin. Awọn ọmọ Asafu, Hemani ati Jedutuni lọkunrin di alo-ohun elo orin ati akọrin, ni ẹgbẹẹgbẹ nlá nlá ti awọn ti n kọ orin egbe ati ti o lo oniruuru ohun-elo orin, awọn ti a ti ọwọ awọn amoye olukọ ti o jafafa kọ́ (1 Kronika 25:1; 15:16-22; 2 Kronika 5:13).

Orin kó ipa pataki kan ninu ijọsin awọn Ọmọ Israẹli si Ọlọrun. A ka a pe: "Hesekiah si paṣẹ lati ru ẹbọ sisun lori pẹpẹ na. Nigbati ẹbọ sisun na si bẹ̀rẹ, orin OLUWA bẹ̀rẹ pẹlu ipè ati pẹlu ohun-elo orin Dafidi, ọba Israẹli. Gbogbo ijọ enia na si wolẹ sìn, awọn akọrin, kọrin, ati awọn afunpè fun: gbogbo wọnyi si wà bẽ titi ẹbọ sisun na fi pari tan" (2 Kronika 29:27, 28). A tun ṣe akiyesi pe pupọ ninu awọn orin Dafidi ni a ti ọwọ awọn akọrin ọmọ Lefi wọnyii: Asafu, Hemani ati Jedutuni kọ.

**Wọn Kò Ni Ipin Ogún Ni Kenaani**

A ya awọn ọmọ Lefi sọtọ fun iṣẹ isin mimọ́ to bẹẹ ti wọn ko fi gba ipin ogún pẹlu awọn arakunrin wọn ni Kenaani. A fun wọn ni awọn ilu lati maa gbé, ti o si ni ilẹ to ni ayika fun itọju ọ̀wọ́ maluu wọn, ṣugbọn wọn ko ni anfaani lati lọ ṣiṣẹ fun ounjẹ oojọ wọn, bẹẹ ni wọn ko si ni ẹtọ ninu ọran ọ̀ṣèlú ni orilẹ-ède naa. Wọn ni lati fi gbogbo ọkàn wọn si iṣẹ isin fun Ọlọrun.

Ọlọrun ṣe itọju awọn eniyan Rẹ ti a ya sọtọ wọnyii daradara. O wi pe Oun ni yoo jẹ́ ipin wọn. Wọn fi gbogbo akoko ati ọkàn wọn fun iṣẹ Rẹ, wọn si ni ẹtọ lati jẹun ni ọwọ́ Rẹ.

Paulu Apọsteli sọ nipa awọn ojiṣẹ Ọlọrun nigba ti o wi pe: "Ẹnyin kò mọ̀ pe awọn ti nṣiṣẹ nipa ohun mimọ́, nwọn a mã jẹ ninu ohun ti tẹmpili? ati awọn ti nduro ti pẹpẹ nwọn ama ṣe ajọpin pẹlu pẹpẹ? Gẹgẹ bẽli Oluwa si ṣe ìlana pe, awọn ti nwasu ihinrere ki wọn ki o si ma jẹ nipa ihinrere" (1 Kọrinti 9:13, 14).

**Laaarin Alàáyè ati Oku**

Ọlọrun n fẹ ki awọn ojiṣẹ Ọlọrun mu ọrọ iye tọ awọn eniyan lọ -- lati "mã tọju agbo." Wọn ni lati ni ifẹ Ọlọrun ninu ọkàn wọn, wọn si ni lati ni Ẹmi (Ọlọrun) ninu aye wọn lati kọ́ awọn eniyan ni ọna ti wọn o fi wọ Ọrun. Ẹrù nlá nlà ni o wà lori ojiṣẹ Ọlọrun lati duro laaarin alaaye ati oku ati lati kilọ fun awọn eniyan pe ki wọn sá kuro ninu idajọ ti n bọ̀.

Ọlọrun sọ fun Esekiẹli pe bi oluṣọ ba ri idà pe o n bọ ti ko ba si kilọ fun awọn eniyan, a o beere ẹjẹ wọn lọwọ rẹ̀. Ọlọrun ti gbe awọn oniwaasu kalẹ bi oluṣọ, wọn si ni lati ni Ẹmi Ọlọrun ninu aye wọn lati kilọ fun awọn ẹlẹṣẹ pe ki wọn ronupiwada ẹṣẹ wọn, ki wọn si mura lati pade Oluwa.

**A Dá Wọn Si Nipa Ijolootọ Awọn Alufaa**

Aarọni ati awọn ọmọ rẹ̀ ọkunrin, ti i ṣe alufaa, rubọ fun awọn Ọmọ Israẹli nigba ti wọn ba ṣẹ̀, i ba má ṣe bẹẹ Ọlọrun I ba ti run wọ́n. Nigba pupọ ni ikú ti ara maa n de ba ẹlẹṣẹ lẹsẹkẹsẹ. Ni akoko kan ti awọn Ọmọ Israẹli kùn si Mose ti wọn si wi pe wọn kabamọ pe wọn ti fi Egipti silẹ, Ọlọrun rán ejo amubina lati bu awọn eniyan naa ṣán. Ọpọ ninu awọn ti ejo bu ṣán ni o kú. Mose gbadura fun awọn ti ejo bu ṣan naa, Ọlọrun si ṣaanu O si wi fun Mose lohun ti yoo ṣe ki a ba le gba wọn kuro lọwọ ikú (Numeri 21:4-9).

Ni akoko miiran awọn Ọmọ Israẹli kùn nitori Ọlọrun pa awọn eniyan buburu kan run nitori ẹṣẹ wọn. Fun ẹṣẹ naa Ọlọrun fẹ pa gbogbo ibudo naa run, ṣugbọn lẹẹkan si i Mose ati Aarọni gbadura gidigidi pe ki Ọlọrun le dariji wọn. Mose sọ fun Aarọni pe ki o fi iná sinu awo turari kan ki o si yara lọ saarin ijọ ki o si ṣetutu fun wọn, nitori idajọ ti bẹrẹ si i wá sori awọn Ọmọ Israẹli nipa iyọnu. Aarọni si yara sare gẹgẹ bi Mose ti palaṣẹ fun un -- ṣugbọn ẹgbaa meje o le ẹẹdẹgbẹrin (14,700) eniyan ti kú na. Gbogbo ijọ ni i ba kú bi kò ṣe pe alufa naa ti duro ni agbedemeji okú ati alaaye" (Numeri 16:41-50).

Bawo ni o ti yẹ fun wa lati dupẹ to fun awọn ojiṣẹ Ọlọrun tootọ ti wọn yọọda lati gbe ọna ti wọn ati ilepa ti ara wọn tì, lati boju to awọn ọmọ Ọlọrun! "Ṣugbọn awa mbẹ̀ nyin, ará, lati mã mọ awọn ti nṣe lãla larin nyin, ti nwọn si

nṣe olori nyin ninu Oluwa, ti nwọn si nkìlọ fun nyin; ki ẹ si mã bu ọla fun wọn gidigidi ninu ifẹ nitori iṣẹ wọn" (1 Tẹssalonika 5:12, 13).

Awọn ọmọ Lefi ti ipò wọn rẹlẹ ju ti awọn alufaa naa ni ojuṣe, ṣiṣai naani eyi ti yoo mu ki awọn eniyan kú. Ọlọrun kilọ pe alejo-kalejo kò gbọdọ wá si tosi Agọ, nitori wọn jẹ alaimọ́, Oun si jẹ mimọ́. Bi ẹnikẹni ba wá si tosi, wọn yoo kú. Nitori bẹẹ awọn ọmọ Lefi pagọ yí Agọ naa ká lati daabo bo alejo kuro lọwọ ikú.

**Idamẹwa Awọn Ọmọ Israẹli**

Ọlọrun fẹ ki awọn Ọmọ Israẹli mọ riri iṣẹ isin awọn alufaa ati awọn ọmọ Lefi iyoku; lati le fi ọkàn imoore wọn hàn, wọn ni lati mu idamẹwa gbogbo ohun-ọgbin wọn ati ti agbo ẹran ati ọ̀wọ́ ẹran wọn wá fun awọn ọmọ Lefi. Pupọ ninu awọn ọrẹ wọnyii ni wọn fi ṣe irubọ; lẹyin ti a ba si ti fi wọn fun Oluwa, eyi ti o ba ṣẹkù ni wọn o jẹ. Idamẹwa gbogbo ibisi awọn Ọmọ Israẹli, akọso ati akọbi - eyi ti o dara ju lọ -- ni o ni lati jẹ́ ipin awọn ọmọ Lefi.

Lati inu idamẹwa ti awọn ọmọ Lefi ba gbà, wọn ni lati yan eyi ti o dara ju lọ lati jẹ́ idamẹwa fun awọn alufaa. Nipa bayii gbogbo awọn ọmọ Lefi ati awọn alufaa ni itọju wà fun daradara ninu ipese ti Ọlọrun ti yàn fun wọn.

Wọn ko gbọdọ gbagbe awọn ọmọ Lefi rara. Ọlọrun yan awọn ase kan, Oun a si maa rán awọn Ọmọ Israẹli leti nigba gbogbo pe ki wọn má ṣe gbagbe awọn ọmọ Lefi ati awọn alaini, ki wọn ba le jẹun pẹlu wọn, ki wọn si maa yọ̀. "Ma ṣọ́ ara rẹ ki iwọ ki o máṣe kọ̀ ọmọ Lefi silẹ ni gbogbo ọjọ́ rẹ lori ilẹ" (Deuteronomi 12:19).

Ṣugbọn bi akoko ti n lọ, awọn Ọmọ Israẹli gbagbe awọn ọmọ Lefi, ọ̀dá si wá sori ilẹ wọn. Nitori wọn kuna lati san idamẹwa ti i ṣe ti Ọlọrun, wahala nla de sori wọn. Ọlọrun ti ṣeleri pe: "Fi ohun- ini rẹ bọ̀wọ fun Oluwa, ati lati inu gbogbo akọbi ibisi-oko rẹ: bẽni aká rẹ yio kún fun ọ̀pọlọpọ, ati agbá rẹ yio si kún fun ọti-waini titun' (Owe 3:9, 10). Nigba ti a ba gbọran si Ọrọ Ọlọrun, a maa n ni idaniloju ibukun Rẹ̀.

Ọlọrun sọ fun wolii Malaki lati wi fun awọn eniyan naa eredi rẹ̀ ti a fi fi orilẹ ede wọn bú, ti wọn si kun fun ebi ati aisan. "Riré li a o fi nyin ré: nitori ẹnyin ti já mi li olè, ani gbogbo orilẹ-ède yi." Nipa bawo ni wọn ti fi já A ni olè? "Nipa idamẹwa ati ọrẹ." Ṣugbọn ko yẹ ki wọn jokoo si ipò ikaanu wọn. Ọlọrun fi han wọn bi wọn ṣe le pada gbadun ibukun nlá: "Ẹ mu gbogbo idamẹwa wá si ile iṣura, ki onjẹ ba le wà ni ile mi, ẹ si fi eyi dán mi wò nisisiyi, bi emi ki yio ba ṣi awọn ferese ọrun fun nyin, ki nsi tú ibukún jade fun nyin, tobẽ ti ki yio si aye to lati gbà a" (Malaki 3:8-10). Ọlọrun ṣe ileri yii fun awọn Ọmọ Israẹli, ṣugbọn awa pẹlu le gbà a, nitori awa ni ọmọ Abrahamu nipa igbagbọ́.

**Eto Ọlọrun fun Ijọ Rẹ̀**

Nigba ti a ba wo Iwe Mimọ lati ibẹrẹ titi de opin, a o ri i pe idamẹwa jẹ́ eto ti Ọlọrun fi n pese fun ijọ Rẹ̀. Awọn eniyan kan gbagbọ́ pé fun awọn Ọmọ Israẹli nikan ni ofin idamẹwa wà fun, ṣugbọn a kà pe nnkan bi ẹgbẹta (600) ọdun ṣiwaju fifun ni ni Ofin, Abrahamu san idamẹwa fun Melkisedeki, alufaa Ọlọrun ọga-ogo (Heberu 7:1-6).

Jakọbu baba awọn Ọmọ Israẹli pinnu fun Ọlọrun ni Bẹtẹli, nigba ti o lá àlá pe oun ri akasọ ti o kan Ọrun, pe oun o san idamẹwa fun Oluwa. "Ati ninu ohun gbogbo ti iwọ o fi fun mi, emi o si fi idamẹwa rẹ̀ fun ọ" (Gẹnẹsisi 28:22).

Nigbooṣe, a fi idi eto idamẹwa naa mulẹ fun Mose: "Ati gbogbo idamẹwa ilẹ na ibaṣe ti irugbìn ilẹ na, tabi ti eso igi, ti OLUWA ni: mimọ́ ni fun OLUWA" (Lefitiku 27:30). A ṣakiyesi pe idamẹwa naa jẹ "fun OLUWA." Ki i ṣe ti rẹ tabi temi, ṣugbọn ti Ọlọrun ni. Bi a ko ba fun Un ni ohun ti i ṣe ti Rẹ̀, Oun ki yoo bukun ayé wa. Ani Ọlọrun tilẹ pe e ni jijale lati dá idamẹwa ti Rẹ duro lọwọ. "Enia yio ha jà Ọlọrun li olè? ṣugbọn ẹnyin sa ti jà mi li olè. Ṣugbọn ẹnyin wipe, nipa bawo li awa fi jà ọ li olè? Nipa idamẹwa ati ọrẹ" (Malaki 3:8).

Awọn Ju san idamẹwa nigba ti Jesu wà ni aye, O si wi pe ki wọn maa ṣe bẹẹ lọ. Ṣugbọn O n beere ju eyi lọ lọwọ wọn. Ki i ṣe nitori wọn ni ifẹ kan lọkan si Ọlọrun ni wọn ṣe n sin In, Jesu si pè wọn ni agabagebe. "Egbé ni fun nyin, ẹnyin akọwe ati Farisi agabagebe; nitoriti ẹnyin nsan idamẹwa minti ati anise, ati kumini, ẹnyin si ti fi ọ̀ran ti o tobiju ninu ofin silẹ laiṣe, idajọ, ãnu, ati igbagbọ́: wọnyi li o tọ́ ti ẹnyin iba ṣe, ẹnyin kì ba si fi wọnni silẹ laiṣe" (Matteu 23:23).

Idamẹwa, eyi ni ni dida idmẹwa owo ti a n gba, dọgba o si tọ́, nitori awọn ti o ni pupọ le dá pupọ; awọn ti ko si ni ju diẹ le da iwọnba eyi ti wọn le dá. "Ki olukuluku ki o mú ọrẹ wá bi agbara rẹ̀ ti to, gẹgẹ bi ibukún OLUWA Ọlọrun rẹ ti o fi fun ọ" (Deuteronomi 16:17). Obinrin talaka ti o sọ owo idẹ wẹwẹ meji sinu apoti ri ibukun gbà lọdọ Jesu ju awọn ọlọrọ ti o le ma mọ iwuwo owo nla ti wọn fi silẹ lara (Marku 12:42-44).

**Pẹlu Ifẹ Atinuwa**

Ọlọrun n fẹ ki a fi silẹ, ki i ṣe nitori a ni lati ṣe bẹẹ, ṣugbọn lati inu ifẹ nla ọkàn wa, nitori a fẹran Rẹ̀. "Nitori bi imura-tẹlẹ ba wà ṣaju, o jasi itẹwọgbà gẹgẹ bi ohun ti enia bá ni, ki iṣe gẹgẹ bi ohun ti kò ni" (2 Kọrinti 8:12).

Bi a ba mọ riri ifẹ Ọlọrun si wa, a o fẹ lati fi gbogbo nnkan ti o ṣe e ṣe silẹ lati ran awọn ẹlomiran lọwọ ki wọn le ni in pẹlu -- idamẹwa ifẹ ati iṣẹ iranṣẹ atọkanwa, idamẹwa fadaka ati wura. A o fẹ lati tan ihin igbala kaakiri gbogbo

aye – nipa akanșe ikede isọji, nipa iwe itankalẹ Ihinrere, pipolowo, nipa ibẹwo awọn alaisan ati awọn ti a hamọ, awọn ọkan ti ko ni anfaani miiran lati gbọ́ nipa Itan naa. A o fẹ lati ran awọn ajihinrere lokeere réré lọwọ. Nipa sisan idamẹwa wa a le ṣe iranwọ fun gbogbo akitiyan wọnyii; lẹyin naa bi a ba wa fi aye wa rubọ ti a si gbadura tẹ̀dùntẹ̀dùn pe ki Ọlọrun bukun irugbin naa ti a gbìn, a o jere awọn ọkàn ti o ṣe iyebiye fun Ijọba Kristi.

**AWỌN IBEERE**

1. Ki ni iṣẹ awọn ọmọ Lefi?
2. Ki ni ó jẹ́ ini wọn?
3. Yatọ si ounjẹ, ki ni awọn ọmọ Lefi n gbà?
4. Bawo ni awọn Ọmọ Israẹli ni ọjọ iwaju ṣe ja Ọlọrun ni olè?
5. Ki ni idamẹwa?
6. Ta ni san idamẹwa ṣaaju akoko awọn Ọmọ Israẹli? Darukọ ẹni meji
7. Njẹ Jesu sọ pe ki awọn eniyan maa san idamẹwa?